Ede Yoruba يوربا

# Aawẹ ipin meji ni

**Aawẹ tí kìí ṣe ọranyan:** ohun ni aawẹ tí ó yatọ si iyẹn

**Aawẹ ọranyan:** ninu oṣu Ramadan, ati awọn aawẹ ìtánràn, ati awọn aawẹ ìjẹ́jẹ̀ẹ́

**Itumọ aawẹ**

Oun ni jíjọ́sìn fun Ọlọ́hun pẹlu kíkó ẹnu ró kuro nibi jíjẹ ati mímu, àti àwọn nǹkan mìíràn tí ó lè já aawẹ lati igba ti alufajari otitọ bati yọ titi ti oòrùn ó fi wọ̀.

## Aawẹ ní origun meji

### 1 Aniyan

| Aniyan aawẹ tí kìí ṣe ọranyan | Aniyan aawẹ ọranyan : |
|---|---|
| ó ní alaafia ni eyikeyi asiko ninu ọsan niwọn igba ti eniyan ò ba ti ṣe nkan tí ó le já aawẹ, ṣugbọn wọ́n o ṣiro ẹsan fun-un lati asiko tí ó ti da aniyan. | Dandan ni kí a da aniyan fun aawẹ ọranyan lati alẹ - iyẹn nipe: Siwaju alufajari - wiwọle oṣu Ramadan ti tó fun wa lati fi da aniyan naa, ọkan si ni ama da aniyan si, adadaalẹ ni kí a fi ẹnu wi i jade. |

### 2 Kíkó ẹnu ró kuro nibi awọn nkan tí ó lè já aawẹ



**Awọn nkan ti nba aawẹ jẹ:**

1- ki a mọọmọ jẹ ounjẹ tabi mu nkan mumu, ṣugbọn ẹniti ó bá gbagbe, aawẹ rẹ ní alaafia.
2-Bíbá obinrin sùn, tí ó ba fi lè jẹ ni ọsan aawẹ Ramadan, ti aawẹ sì jẹ ọranyan fun ẹni naa, o gbọdọ ṣe ìtanràn tó nipọn
3-Dida àtọ̀
4-Nnkan tí ó bá ní ìtumọ̀ ounjẹ ati mímu, gẹgẹbi àwọn abẹ́rẹ́ tí ń fun ni ní ounjẹ
5-Yiyọ ẹjẹ kuro lara pẹlu ìdógò 6-Imọọmọ bì 7-Jijade ẹjẹ nkan oṣu ati ẹjẹ ibimọ

**Ninu awọn nkan tí ó jẹ ẹtọ fun alaawẹ**

- Titọ ounjẹ wò nitori pé a bukaata si
- Gbigbe itọ mì
- Ìwẹ̀
- Rirun pákò
- Lilo lọfinda
- Gbigba nkan tutu si ara

## Awọn majẹmu ti nmú aawẹ di ọranyan fún ni

| | |
|---|---|
| 1-Islam | 2-Ilaakaye |
| 3-Bíbàlágà, ṣugbọn ní ti ẹnití kò tii bàlágà, a ó gba a niyanju lati maa gba aawẹ, awọn obi rẹ ó si maa pa a laṣẹ fun-un | |
| 4 -Igbenuulu: Kìí se ọranyan fun arinrinajo lati gba aawẹ, ṣugbọn ó dara fun un kí ó gba aawẹ niwọn igba ti ko ba ti ṣoro fun un, nitori nkan ti Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – ṣe, ati nitori pe ohun ni o yara julọ lati tete mu aawẹ kuro lọrun, ohun ni o si rọrun ju fun eniyan, ati ki eniyan le gba oore oṣu aawẹ naa. | |
| 5 - Alaafia | 6 - Ki obinrin má si ni asiko nkan oṣu ati ẹjẹ ibimọ |

**Awọn eewọ tí alaawẹ kò gbọdọ ṣe ni:**

1 - Gbígbé kẹ̀lẹ̀bẹ̀ mì, ko si gbọdọ tú nu pẹlu rẹ̀
2 - Fifi ẹnu kiisi obinrin, iyẹn fun ẹni tí kò ní ifọkanbalẹ nibi bibajẹ aawẹ rẹ̀
3 - Ọrọ̀ èké (ohun ni ṣiṣẹ gbogbo nkan eewọ)
4 - Aimọkan (ohun ni iwa omugọ)
5 - Ìdààwẹ̀pọ̀ (iyẹn ni pé ki eniyan má tu nu fun ọjọ meji léra wọn).

**Awọn nkan ti a korira rẹ̀ ninu aawẹ:**

1 - Fifi omi pupọ ju yọ ẹnu ati fifa omi pupọ ju si imu
2 - Titọ ounjẹ wò lai ni bukaata si i